# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LA WA

No. 572 MONDAY APRIL 6, 1964 (2D)

## Ọdaran Kan Bẹ Adajọ Pe Ki O Tete Ju On Si Ẹwọn

ILESHA:— Ẹrin arin gbokiti ni gbogbo awọn ero ti o pejọ si ile ejọ kekere kan nilu Ilesha nrin bi ọdaran kan ti awọn ọlọpa pe ni "Ọrẹ wa" ti sọ fun Adajọ ile ẹjọ na Ọgbẹni M.B. I. Layiwọla wipe "Mo bẹ yin mase da mi duro mọ rara, ki ẹ tete fi mi ranṣẹ pada si ile mi, ti iṣe ọgba ẹwọn.

Ọdaran yi, Saka Atanda sọ ọrọ yi nigbati adajọ ni on fẹ lati mọ bi iwa ọdaran yi ti ri tabi bi o ba ti lọ si ọgba ẹwọn ri.

Were ni ọdaran na sare naro ti o si tun sọ pe ki awọn ọlọpa mase ṣe wahala rara, Ọgba ẹwọn ki iṣe alejo on, ko si ọgba ẹwọn ti on koi ti wọ ri.

Ẹsun ti awọn ọlọpa fi kan ọdaran yi nipe o fọ ile Alfa Yisau Akande ti opopo Imogun ni ilu Ilesha ti o si tun jale iwe Korani meji ati awọn aṣọ wiwọ ti iye owo rẹ jẹ pọnun meje ati sile mẹwa (£7 : 10/-

Nigbati adaiọ bi Ọdaran na lere bi o jẹbi tabi ko jẹbi, Ọdaran na gba wipe on jẹbi ni adajọ ba ṣe idajọ pe ki o lọ si ẹwọn ọdun kan oniṣẹ-aṣekara.

### Alhaji Tafawa Balewa Sọ Pe :

# ỌLỌLA AZIKIWE KI IṢE ẸNI ABUKU !

EKO:- Gbẹgẹdẹ gbina ninu Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria ni ipari ọsẹ ti o kọja yi nigbati Alhaji Abubakar Tafawa Balewa, Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria mba awọn ọmọ Ile Igbimọ sọrọ, lori ẹsunna-owo ti Apapọ Ijọba yio na fun Aafin Ọlọla Ọmọwe Nnamdi Azikiwe, Olori Apapọ Ijọba Naijiria

Gbogbo Ile lo palọlọ ti pẹkẹ ko si mi, nigbati Alhaji Abubakar nba awọn ọmọ Ile Igbimọ na sọrọ ti gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na si tẹti leko

ẸNI ABUKU

Alhaji Abubakar sọ wipe Ọlọla Nnamdi Azikiwe, ni Olori Apapọ Ijọba Naijiria o tọ, o si yẹ ki gbogbọ orilẹ-ede Naijiria, o ma a bu ọla fun un pẹlu irẹlẹ ati ẹyẹ bi o ti tọ ati bi o ti yẹ.

O tun ṣe alaye pe, Ọlọla Azikiwe ki iṣẹ ẹni abuku gẹgẹbi o ti ṣe jẹ wipe on ni Opa-ogo ati asiwaju fun orilẹ-ede Naijiria ti gbogbo aiye nwo lokere bi awojiji ẹnikẹni si gbọdọ fi ọwọ ti o tọ ati eyi to yẹ fun un nile ati ni ẹhin odi

Alhaji Abubakar tun ṣe alaye siwaju ninu ọrọ rẹ pe, iṣẹ gbogbo wa gẹgẹbi ọmọ Naijiria lati ri wipe ẹnikẹni ko huwa arifin si Olori Ilẹ Naijiria.

O wa ṣe kilọkilọ fun gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na pe, nigbati awa alara ko ba ri aṣiwaju wa fin, awọn Orilẹ-ede miran ko le ri fin rara

Siwaju sii, Alhaji Abubakar ni "Bi onigba ba pe igba rẹ ni peekaa, awọn ara ode a si ba a fi igba na kolẹ si ori akitan.

Oni nigbati a ko ba fi aye olori ilu wa ṣere, awọn ara ode ko ni ba wa fi ṣere pẹlu iru aye ti a ba si fi olori wa si, ni gbogbo aiye yio ba wa fi si pẹlu.

Ọrọ yi ni esi ti Alhaji Abubakar Tafawa Balewa sọ fun awọn ọmọ Ile Igbimọ nigbati nwọn bu eto ẹsunna-owo fun Aafin Ọlọla Azikiwe.

Siwaju eyi ni awọn ọmọ Ile Igbimọ na ti sọ wipe ọgbọn ọkẹ pọnun (£63,160) ni iye owo ti awọn yio fi silẹ fun Ọlọla Azikiwe lati ma a na. fun Anfani rẹ ninu ọdun yi titi di ọdun ti mbọ yi. (1964-1965)

Ọkan ninu awọn ọmọ Ile Igbimọ na sọ wipe, owo yi ni Ọlọla Azikiwe yio ma a fi ṣe alejo lati ọdun yi titi di ọ d u n ti mbọ, owo na ko si ju eyiti o le na tan ki o to digbana lọ.

AGBỌRỌSỌ

Siwaju eyi ni Dọkita Kabu Ezera, ọkan ninu



Alhaji Abubakar Tafawa Balewa
Alakoso Ijọba Apapọ Naijiria



DOKITA NNAMDI AZIKIWE
Olori Apapọ Ijọba Naijiria

awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ninu ile igbimọ na ti sọ wipe, o yẹ ki Ijọba Naijiria ki o ni Ile-iṣẹ kan ti yio ma a da esi ọrọ pada, si gbogbo awọn ti nwọn ba nsọ oko-ọrọ si Ọlọla Azikiwe.

Gẹgẹbi alaye, awọn ọmọ Ile Igbimọ na fi han gbogbo Ile wipe, "Ọrọ arifin" ti awọn Ọba kan ni Ipinlẹ Ariwa sọ si Ọlọla Azikiwe laipẹyi ya ẹnikẹni lẹnu, ti o si jẹ wipe gbogbo awọn ti nwọn mọ iyi ati aye Olori Ijọba, o jẹ iyalẹnu fun wọn.

Awọn enia na ni iru ọrọ ti awọn Ọba na sọ, jẹ ọrọ "aifi-ẹni-pe-ẹni, ati aifi enia-pe-enia, ti ara oko fi iṣan bantẹ wọ arin ilu."

O si yẹ ki awọn ni ẹnikan ni ọtọ, ti yio ma fun iru awọn enia na ni esi ọrọ won ti nwọn ba tun sọ ni ọjọ iwaju.

IDUPẸ

Ọgbẹni Akwiwu sọ wipe

Wo Oju Ewe Kẹfa

# IWA IBAJẸ LARIN ILẸ WA ATI ẸSAN

## Lati Ọwọ S. O. Jaiye

Ọrọ mi ninu iwe oni wa lori Iwa wa oni ati ẹsan fun iwa ti a nhu larin ile, ilu ati orilẹ-ede wa. Mo dorikodo ninu ironu mi lati ṣe ayẹwo awọn iwa buburu to wa larin wa Ironu yi jaminikoro kuro ninu orun a sun gbadun Ara mbẹ mi mo nhọ gbogbo ara mi fun ihunra iwa ibi ti o wa lode oni yi Alafẹhinti ko si mọ alanu jina sinu aiye abanidaro di alarokakiri, Ohun majẹ a gbọ di ohun ti a ntu silẹ lari ọja ti a si fi nrẹri ya ·gi.

Bamikojọpọ ko si mọ bi koṣe bamijẹ ti nfi gigiṣẹ tu ebe ti a fi irora kọjọ pọ Gbogbo awọn iwa ibajẹ wọnyi di ohun ti ẹmi mi nsọkun le lori Bi mo ti nronu ti mo si fi ọwọ le ẹran ni ohun kẹlẹ kan bi mi lere pe Njẹ ẹsan ko ni pẹ de bayi?

Mo wa bere wipe kini a npe ni ẹsan? Ẹsan jẹ ere fun ohun gbogbo ti a ṣe ni ikọkọ tabi ni gbangba iba ṣe rere buburu ẹsan yo ke fun gbogbo iwa ibi ti a nhu lode aiye wa yi.

Bi iwọ ba jẹ ọba ilẹ wa loni yi ti iwa rẹ to nhu ko dara fun rikiṣi ati ai fi ọkan awọn enia rẹ balẹ ranti ọba Ga lode Ọyọ.

Ki o lọ ronu lori iwa atijọ ki o si ranti ohun tode ba kẹhin ọjọ aiye rẹ fun idi eyi lọ ronu iru ẹsan to ba kẹhin ọjọ aiye rẹ

Lọ ronu lori iru awọn ọba buburu to wa ninu iwe Ọlọrun si ka nkan ti o je ẹsan fun wọn kẹhin.

### OṢELU AFIKUPANI

Bi o ba jẹ oṣelu ti o nhu iwa fikupani tabi iwa ọdalẹ mo fẹ ki o lọ ronu lori awọn oṣelu miran bi Musulumi ati Hitler.

Awọn wọnyi mu aiye lati oke de ilẹ nigba aiye wọn.

Bi o ba jẹ pe iwọ nba ọmọ ọlọmọ jẹ eyi ni pe kio ma fun awọn ọmọ ọlọmọ ni ọti bọlugi ati tabaa sinni niwin, nigbati o jẹ wipe o pa awọn ọmọ tirẹ mọ si ilu kan lati ma ran wọn ni ile-



Ogbẹni S O Jaiye

·e giga fun ire wọn lẹhin ọla.

Ranti wipe ẹsan ohun ti · nṣe fun awọn ọmọ ọlọmọ Laisi aniani ẹsan mbọ wa dahun lori awọn ọmọ tirẹ lẹhin ọla.

### ỌRỌ KIKOJỌ

Ọpọ enia lo wa ti ko mọ pe ẹsan wa fun gbogbo nkan ti nwọn nṣe ti nwọn si nhu niwa. Ti o ba ṣe pe nwọn mọ ni o yẹ ki nwọn jawọ ninu iwa ti o le fa ẹsan buburu wa ba wọn ati awọn ọmọ wọn lẹhin ọla.

Ki akowo jọ ni ọna aitọ ki a si fun ọmọ ẹni ni ẹkọ to yẹ koro; eyi ko wipe ki ọmọ ẹni maṣe mọ iwe; ṣugbọn ẹsan to wa nibẹ nipe ti akoko ire ati ere ba wa de ki ọmọ ẹni le ni ẹmi gigun lati lo anfani yi o sa ba ma nṣoro pupọ.

Nitori ohun ti a npe ni ẹsan yo dahun. Ọlọrun papa sọ ninu ọrọ Rẹ pe Ọlọrun Ẹsan ni On ati pe gbogbo ohun buburu ti a ba ṣe labẹ orun ẹsan yo dahun.

Iwe Mimọ Oluwa sọ pe, Egbe ni fun iwọ a ba ni jẹ ti a ko ba Ọ jẹ nigbati wọ ba dẹkun ati bani jẹ ni gbana ni ao dide si ọ

Mo mọ daju wipe otitọ ni ọrọ Ọlọrun yi jẹ. Nitori na ara, ọre, ojnlumọ ronu lori ọrọ Iwa ibi ati Ẹsan lori iwa ti a nhu lọjọ aiye wa gbogbo.

Mọ daju pe iṣẹ ibi ti o nṣe lode aiye ko ni lọ lai si ẹsan ninu rẹ. Ti ẹsan ba si de ibanujẹ lo si nmu wa ba ni ninu aiye.

### ỌTI BỌLUGI

Mo nrọ nyin pe maṣe fun awọn ọmọ ọlọmọ n' ọti bọlugi ati taba sọ, agba ati ewe di iwere. Gbiyanju lati wa ọna rere fun awọn ọmọ ọlọmọ ti o ba fẹ ki awọn ọmọ tirẹ joguu iṣẹ rere ọwọ rẹ.

Kini de ti awọn oṣelu wa nwa abọ lati ọdọ awọn ọdọ tabi ewe wa kiri. Iwọ oṣelu fẹ ki awọn ọmọ ọlọmọ ma ṣe ọmọ ogun rẹ lati ma tele ọ kiri fun idabobo lọwọ awọn ọmọ ọta kakiri.

Ṣugbọn ọmọ tirẹ wa ni ilewe Giga ni ilu eyinbo. Ṣe ti awọn ọmọ ọlọmọ ba ru apamọ rẹ titi ti o ba ya wọn, nwọn o tun ma ru apamọ ọmọ rẹ kiri.

Eyi nkọ R o awọn iṣẹ rẹ wo dada. Owo ti o fi ra taba amuyawere ati ọti bọlugi fun awọn ọmọ ọlọmọ, owo yi to lati ran wọn lọwọ lati ni ẹkọ to ye koro lati wa onjẹ ojọ wọn kiri. G a awọn ọrọ wọn yi ro.

Odigba o.

---

## Alfa Raji Adegbọla Lọsi Mẹkka

Lati ọwọ OMỌ—AYAN, Eko.

MUSHIN:- Ẹnu kọ irohin sara ti Alfa Raji Adegbọla ṣe ni ọjọ Isimi ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu yi ninu ile rẹ ni Onifade Street Mushin fun ipalẹmo irinajo lọ si Mẹkka–Mẹdina ti o lọ ni ọjọ Isinmi ti iṣe ọjọ karun oṣu kẹrin ọdun yi.

Alfa Raji Adegbọla ni olori Alfa gbogbo Imale ọmọ Oke-amu ti owa ni Eko yi ki oto di ọjọ sara yi ni oti ṣe alaye fun awọn ọmọ Imale Oke-amu ti o wa l'Eko yi lori ati lọ si ilẹ Mimo yi Mẹkka

ADURA

Gbogbo ọmọ ilu Oke-amu ni opeju si ibi Adura pataki yi ati pe oriṣiriṣi iranlọwọ ni o ṣelẹ ni asiko yi atipe ni asiko yi ni gbogbo awọn asiwaju ti otẹle Alfa Raji Adegbọla yi dupẹ lọwọ Ọlọrun pe, awọn ri iranlọwọ lati ọdọ Ọlọrun tio yan Alfa Raji Adegbọla ni ẹni akọkọ fun ilẹ mimọ na.

Nigbati ọjọ ati lọ si ilẹ mimọ yi ti ku bi osu kan ni alfa Raji Adegbọla ti lọsi ilu rẹ Oke-amu ni agbegbe Ọyọ gbogbo awọn agbalagba ilu ati awọn alfa jankajankan ati paapa julọ awọn ẹgbẹ ọdọ ṣe aṣeyẹ fun Alfa Raji Adegbọla pẹlu ebun pataki lati ọdọ ẹnikọkan wọn.

Ninu awọn enia na ni wọn yi Imamu Alfa Nafiu alfa Aminu, alfa Gbadamọsi, ati Alaga ilu Oke-amu Alaka Oladeji.

Bakanna ni awọn oriṣiriṣi ẹgbẹ ti o wa ninu ilu Eko ṣe iranlọwọ pupọ fun alfa Raji Adegbọla to bẹ gẹ, ti ofi wu ọpọlọpọ enia lori ti nwọn ti ṣe ipinnu pe awọn setan lati mu aṣọ ni iranti lilọ si Mekka alfa Raji Adegbọla

Ẹgbẹ ọmọ Imale Oke-amu (Movement In Islam) Irẹpọdun Society Ikẹ-Oluwa, Ọmọnijogunọla, Ọbanibaṣiri, ẹgbẹ Idẹra, (Federal Union) gbogbo wọn ni awọn peṣẹ patapata ni ọjọ idagbere alfa Raji Adegbọla yi.

### ASALATU FUN ONIṢẸ ỌLỌRUN

Ki Oluwa mu gbogbo awọn Alhaji lọ layọ, ki osi mu wọn pada wa ba wa ni alafia

# IWE SI OLOTU

## A o Tunka Enia ninu Ọdun Yi?

Olotu, ẹ ku ewu ọdun Ajinde. Ọlọrun yio jẹ ki ajinde ara ki o mọ jẹ fun nyin amin inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba laye diẹ ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati fi ọrọ mi yi sita fun gbogbo awọn onkawe nyin gbọ. Nitoripe ọrọ na ko ye wa mọ ra ra.

A ka arawa ni idunta ko loju-tu, a tun ka arawa ni ẹsin ba-kanna ni gbogbo rẹ ja si, o yẹ ki oju ki o maa ti wa, ka wipe bi ati gbọn to, ti a si mọ iwe to ti a tun loye lori to ni Naijiria, ko wa jẹ wipe nkan ti ko ita nkan ni yio mọ da wa ra.

Ko si ojulowo ọmọ Yoruba ti inu rẹ dun si ipo ti ilẹ Naijiria wa loni yi eyiti o wa buru julọ nibẹ ni ti ao fohun sọkan lori abayọri enia kika. Gbogbo awọn orilẹ-ede toku ni nwọn nbu enu atẹ lu wa.

Mo bẹ ẹnyin aṣiwaju wa pe, ki ẹ ran wa lọwọ ki ẹ le pa imọ nyin pọ, ki ẹ ye gbe wa lẹmi gbo-na mọ. Bi oju ko ba ti de oju a ma a ti ara ile rẹ.

Ọrọ emi gba, emi ko gba ti sọ Naijiria di yẹpẹrẹ latin orilẹ-ede yoku ẹ ma fi ti nyin rẹ wa la-ra mọ ẹ pamọ pọ, ki e fi ohun sọkan.

Ẹ ṣe pupọ Olotu

Emi ni,
J. T. ILỌRI
Lọndọnu

## Ẹmi ko pe meji

Mba sọpe bi Olotu ba le gba mi laye diẹ nwọn iba ranpẹ ni-nu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi awọn Ọlọpa Aṣọmọto pe ki nwọn jọwọ ki nwọn ma a moju-tọ awọn onimọto ti nwọn nsare



Alhaji Y. A. Disu

isakusa lọna Agege ati Mushin.

Ẹmi ko pe meji. "Fewu ina ki i si ipa awodi". A bẹ awọn onimoto (awamọto) bọọsi tabi bọọlẹkaja ki nwọn jọwọ ki nwọn ye ko ero ti o nlọ si Agege tabi ọna Agege kọja ata, ki nwọn si ye wa mọto ni iwakuwa mọ.

A ko fẹ ijamba mọto ma a ṣe ọmọ enia rara.

A bẹ Minista Alamojuto iṣẹ mọto ati awọn Ọlọpa ti o wa labẹ rẹ ki nwọn ba wa ṣe ikilọ pupọ fun awọn awamọto na.

A dupẹ o,
Emi ni,
HADJI Y. A. DISU
Eko.

## Ẹ Ku Iṣẹ o

Ẹ jọwọ gba mi la ye ninu iwe Irohin nyin oloyinmọmọ lati le ko iwe mi yi ... fun gbogbo



Alhaji A. F. Masha

wọn onka we irohin nyin.

Mo fẹ ki awọn Igbimọ Ibilẹ ilu Eko kuṣẹ fun iṣẹ ribiribi ti nwọn ṣe nipa dida ọda si gbo-gbo oju ọna arin ilu Eko.

Ṣebi Yoruba nipa lowe pe "kuṣẹ ni mu ori iṣẹ ya"

Ọlọrun ti o fun nyin ni agba-ra lati fi ṣe eyi yio si tun maa ran nyin lọwọ o.

Mo dupẹ lọwọ nyin o Olotu

Emi ni
BABATUNDE OYE

## Otitọ Koro

Olotu, Ayọ nla ni yio jẹ fun mi ti ẹ ba le gba mi laye lati te iwe mi yi jade ninu iwe Irohin nyin oloyin-mọmọ fun gbo-gbo awọn enia ti ori wọn pe la ti ka, ti nwọn si ri ẹkọ iwe na kọ.

Ohun iyalenu ni o jẹ fun mi nigbati mo gbọ lati inu ero re-dio pe Ijoba Ipinle Iwọ Orun fi Ofin pajawiri de Are ti ọgbẹni Ogunde ṣẹṣẹ ṣe ti nwọn npe ni "Yoruba ronu"

A ṣe otitọ ni ara awọn ti nṣe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria kọ otitọ, ṣebi otitọ ni are ti Ogunde nṣe?

Mo fẹ ki ẹ mọ pe igbẹhin ni aleyo nta.

Mo dupe lọwọ Olotu fun aye ti ẹ gba mi.

Emi ni
LAWANI KOLADE
Ogbomọṣhọ

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yato patapata si awọn

**RICHELẸT**

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' bi Mọn-mọnọ

Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgebi awọn Onibara wa ti mo irufẹ awọn egbogi ba wọn yen a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣe fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mo daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se o, La-kuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Edọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Eṣ Amodi Apo ile itọ, ẹhin diduẹ tabi ibaradi riro pẹlu Egbon RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nbo ẹjẹ ara rẹ patapata yio si n ẹjẹ rẹ mọ toritoni pẹlu.

Ṣa dan igo re kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomi-ran pelu.

Bere egbogi aejbina Richelet yi ni ṣọbu awọn
Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji)

## Igbimọ Atunto Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

GẸGẸBI ati fi aṣẹ fun mi lati ọdọ awọn Igbimọ atuneto egbẹ Imọle Aiye pe, nwon ti tu ẹgb Imọlẹ Aiye tele ka, a si ti tun da omiran silẹ n torina ti o ba ri pe o fẹ jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbe te tun yi ki o kọwe si mi ki o si ri pe o wa si Ipade ni ojo kọkanla oṣu kẹrin (11/4/64) ni dede agogo mẹta ọsan.

Ẹgbẹ yi yatọ si ti atẹhinwa a si tun ti ni ofin titun miran. Eyi si ni awọn ere ti ẹgbẹ titun na yio ma se'

1. Lati maa kọ awon ọdọ ilẹ yi ni ọna bi a ti nkọ irohin, itan, oro sinu iwe Irohin lati ọdọ awọn Ojogbon oniwe Irohin
2. Ere bi Boolu alafesẹ gba, Table Tennis, Swim-ming, Entertainment, Ayo Iṣẹ, Draft Ludo Picnic ati opolopo ewon nkan miran ti eo ma a gbọ ni ipade.

Nitorina ti o ba fe tun jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ẹgbẹ titun yi ki o wa si ipade ni ọjọ 11/4/64 ni nọmba 16, Bamgboṣe St., Lagos, Ao si tun yan awọn alaṣẹ ẹgbẹ titun

Eyi ni oruko awọn Igbimọ atunto ẹgbẹ Imọlẹ:—

1. J. Ọla. Okunlọla
2. Latifu Babalọla
3. Sedu Olupo
4. Abudulahi Awẹlẹnjẹ
5. Tmothy Akins

Ẹ jọwọ, ẹ tete de ipade o.

# Onitakisi Kan Wa Mọto Rẹ P'ania

EKO:— Anu ṣe gbogbo ero ti o pejọ si ile ẹjọ giga kan ni Eko larin ọsẹ ti o kọja yi nigbati Ọgbẹni Saka Aiyeọla ti ṣe ọkan ninu awọn ẹlẹri Ijọba sọ fun ile ẹjọ pe Tunde Ọlabinjọ ti ṣe dẹrẹba takisi ni o fi mọto rẹ kọlu Taiwo Oluṣeyi ti o si tẹ ẹ pa bamubamu

Saka nfi han ile ẹjọ na wipe on jẹ ọkan ninu awọn ero mẹfa ti dẹrẹba yi gba sinu takisi rẹ ni ọjọ na.

Bi on ti ri pe dẹrẹba yi fẹ mu wa mọto rẹ sare pupọ on kilọ fun lẹ meji, ṣugbọn ko bikita rara.

O tun sọ wipe bi takisi na nti mura leti kọja mọto miran ni o ba kọlu Taiwo Oluṣeyi ti o gun kẹkẹ basikulu, wọn ṣugbọn dẹrẹba takisi yi ko ti lẹ duro diẹ lati wo ẹniti on kọlu rara.

Ṣugbọn bi awọn ti awọn wa ninu takisi yi ti ri bẹ, ni awọn ba fi agbara da duro, ti awọn si da pada si ibi ti o ti kọlu oni kẹkẹ yi.

Bi mọtọ na ti duro ni dẹrẹba na ba kọ fi ogbọn salọ ti awọn si tun fi ọlọpa mu.

Ẹlẹri Ijọba miran ni Michael Alake ti iṣe iṣẹ ọlọpa o sọ wipe on ni on le dẹrẹba ọdaran yi mu nigbati o fẹ salọ lẹhin igbati o kọlu Oluṣeyi tan.

Ṣiwaju ọdaran dẹrẹba yi Ọlabinjọ ti sọ wipe on ko jẹbi ẹsun apania ti nwọn fi kan on.

Adajọ ti yẹ ọjọ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ iwaju.

Bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si ẹ tun maa gbọ ninu iwe Irohin wa.

## ★ YẸ IRAWỌ RẸ WO ★

AQUARIUS Jan 20-Feb 18-Ọjọ oni dara. jẹki pari gbogbo awọn rogbodiyan ti o ti wa nilẹ, ṣugbọn ṣora ki o maṣe tan fọwọ fa ijọngbọn titun miran kan eyi ti o ti wa nilẹ.

PISCES Feb 19-Mar 20-Ọgbọn ati ifẹ ni ki o ma fi ba awọn olufẹ rẹ gbe pọ, bakanna ni ki o ma ṣe pẹlu awọn ẹbi ati ojulumọ rẹ pẹlu irẹpọ dara.

ARIES Mar 21-April 19-Ọjọ oni dara, ṣugbọn ibinu diẹ ko ni ṣe alaiwa, oni dara lati ba enia ṣe adehun, tabi lati kọwe si idalẹ tabi lati kọwe ẹbẹ iṣẹ.

TAURUS Apri 20-May 20 Ọjọ oni dara fun gbogbo nkan ti o ba jẹ ti ara rẹ, kọ lati ma ṣe iranti ọrọ, maṣe fi gbogbo ọrọ ṣe igbagbe, ki o si mura si iṣẹ rẹ.

GEMINI (May 21 - June 21) Orire airotẹlẹ kan yio de si ọ loni gbogbo iṣoro ti o wa niwaju ni yio yanju, maṣe gbagbe iṣẹ rẹ, ma si ṣe fi ọrọ owo ṣere.

CANCER (June - July 22) Ṣọra loni ki a ma ba mu ọ binu ainidi, maṣe ja, nitoripe ohun ti o nrọ ọ binu yio, si tun wa petu si inu rẹ.

LEO(July 23 - Aug 21) Ọjọ oni dara, iwọ yio gbayi larin awọn ọṣiṣẹ ẹlẹgbẹ rẹ, iwọ o si tun pari ija kan ti o ti wa niwaju rẹ.

VIRGO (Aug 22 Sept 22) Maṣe bu enia dipo ti iwọ yio fi jẹ loni, nitoripe ni gbogbo ọjọ oni, ọrọ ija ati asọ ti yio ma a ṣe ọ, bẹni iwọ ko gbọdọ ja.

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Ire ni iwọ yio ma ba pade ni gbogbo ọjọ oni, alafia yio to ọ, ara rẹ yio si ma, ohun gbogbo ti o ba ṣe loni, yala tabi ire, ajẹgun li yio jẹ.

SCORPIO (Oct 24 - Nov 22) Ohun to dara fun ọ loni, obinrin ni ki ọ ma wa ki o to di wipe arẹ mu ọ.

SAGITTARIUS (Nov. 23 - Dec. 21) Kiṣe ọjọ gbo gbo ni ọdun Ileya, ọjọ oni dara fun ọrọ ile ajeji. Yan asiko ọjọ ti iwọ yio simi nitori isimi dara fun ọ.

CAPRICORN (Dec. 22 - Jan. 19) Orire airotẹlẹ kan yio de si ọ ni akoko owurọ, ohun kan ti o si ngbeo yio jẹ ọ ṣe. Itẹlọrun yio wa fun ọ pọlu.


# Gbanjo Gbanjo Gbanjo!

Eyi ni lati kede fun gbogbo awọn ONIBARA wa jake jado agbaiye pe ao bẹrẹsi ma a ta Ọja gbanjo wa fun ti Ọdun EASTER ati ILEYA gẹgẹbi iṣe wa lọdọọdun Ohun ti o tun mu wa tete bẹrẹ gbanjo yi ni pe, iwe ti, o nti ọdọ awọn ONIBARA wa wa lati:-

**Ghana, Abijan, Cotonou, Lome ati Portnovo**

Ko ni'ye pe ki a tetebẹrẹ GBANJO na.

TETE WA RA TIRẸ LONI

OJA GBANJO NA BẸRẸ LATI 2nth MAC.-30th APR



dilwe Egbogi Ajẹbidan 25/- 22/6d

Iwe Ilana Ifa, Iyanrin tite Etutu ṣiṣe 21/- di 18/-

Iwe Afọṣẹ Iṣẹda ẹ Yoruba ati Psalm Isegun Aje 4/6d di 3/-

Iwe Ala Nla 7/6d di 5/6d

Iwe Ala ati Iwadi Nkan 2/6 di 2/-

Turari Isegun .. jẹ10/6 di 8/-

Certificate of Appreticeship 7/6d di 5/-

Tailor's Measurement Book 7/6d di 5/6d

Iwe Itan Ala 2/6d di 1/-

Iwe Itumọ Ami Ara 4/6d di 3/-

AKIYESI:— Ẹnikẹni ti o ba ra ninu awọn ọja yi yio gba TURARI IṢẸGUN AJẸ" lọfẹ lati fi dan wa

**Shoyinka**

S2/99 Shittu Street
Ibadan


# E ma a ka Irohin Imọlẹ lojojumọ


BERE OJULOWO EGBOGI:—

## Congrevds' Female Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn obinrin ti o ba ni iyọnu tabi amodi inu rirun nigbakugba tabi ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudu ara tabi aikotọ ẹjẹ lara inu ẹ gbigbona nigbakugba Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ti oma nfa oyi - oju Ilaogun ara ẹṣẹ ara sisọn, ẹfori abi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo O b i n r i n gẹgẹbi Ajo fun ilera ati oriṣiriṣi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni in nigbakugba pelu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI JO TI WON NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba Iailai ki awọn Oriṣiriṣi rọbirọbi egbogi ti wọn nko wa lisisiyi to de awọn ag al gba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egb gi yi bi otutu ikọ iba, orere lukuluku onigbameji ti a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egboei ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ opo-ila-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-le-itọ egbogi aju didun tabi ti ọwa-ọfun didun, ati oriṣirisi omira pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
P one:h Nigeria, (Oja Ita Faj)

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

### ỌJỌ AJE APRIL 6 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Ikẹja, Agege, Ebute-Ero Ọjọ Ajido |
| ABEOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọla |
| IBADAN | Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo, Lalupọn, Ajegunlẹ Owode Igbo-Ọra |
| IJEBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, |
| IJESHA | Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, |
| EGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki, Ijẹbu-Ijẹsha |

### ỌJỌ IṢẸGUN APRIL 7 (TUESDAY)

| ILU | ILU |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ. | Oyingbo |
| ABẸOKUTA | Ijoko Ibẹrẹkodo, Asu, Wasnimi, Owode |
| IBADAN | Akẹroro, Idọfin, Lagun, Sagbẹ Ogunjana, Mọlete |
| IJẸBU | Aiyepe, Sagamu, Itaosu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ |
| JẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunwa, Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

### ỌJỌ'RU APRIL 8 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye |
| ABẸOKUTA | Atan Agbado, Ifọ Itori, Itoku Fabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fẹdẹgbo, Oyedeji, Ogburo, Ẹgbẹda Babalokuta, Ijaiye Orile. |
| IJẸBU | Ilishan, Isara, Imodi. |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọ. |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Oda. |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun. |

### ỌJỌ ỌJỌBỌ APRIL 9 (THURSDY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkọ Omida Itwọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwọ Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idoko Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| KITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

### ỌJỌ ẸTI APRIL 10 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikẹja, Agege |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajọl |
| IBADAN | Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imope Iwara Ejiro, Odo, Ibokun |
| ẸGBADO | Ijẹbu-Ijẹsha, Lasilo-Idiẹmi |
| EKITI | Okemẹsi, Ifaki. |

### ỌJỌ ABAMẸTA APRIL 11 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, Ejinrin |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Bẹrẹkodo, Aṣu, Wasinmi, Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun Ṣagbẹ, Ogunjau, Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu, Ogere Irolu, Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdua, Sunwa, Iboro, |
| EKITI | Ilogbo, Ishan. |

### ỌJỌ AIKU APRIL 12 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Ẹpẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Fẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta' Ijaiye-Orile |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpẹ ṣara, Imodi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Aiyetoro, Ado-Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

### ỌJỌ AJE APRIL 13 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, Badagary |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Sodẹkẹ, Omida Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonkọ, Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun—Ọwa, Ẹruwọn, Omu. Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko, Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJON' GBORO

### AWKA

Jinnijinni dabo gbogbo enia nig! ati obinrin kan wọle sun ni alẹ, ti ejo kan si lọ bu obinrin na, Iya-afin Oyibidi Dobna jẹ, obinrin na ku ki wọn to gbe de ile Iwosan.

### JOHANNESBURG

Ọgbọn enia lo ku bamu-bamu ninu ijamba mọto loju ọna, ti omi okun si gbe enia mọkanla lọni ọjọ ọdun Ajinde ti o kọja yi.

### MOSCOW

Ijọba Rọsia ti tun yin Bọmbu Oloro kan si oju ọrun eyi ti nwọn fẹ mọ bi agbara rẹ ti to lati fi jagun.

### IBADAN

Ọgbẹni Akinyẹmi sọ pe ẹgbẹ Alakukọ ati ẹgbẹ Afẹni.ẹre fe papọ di Ọkanṣoṣo ki ẹgbẹ na o le ba ẹgbẹ Dẹmọ ja doju iku, ki nwọn o ma ṣi ṣe gburo ẹgbẹ Dẹmọ na mọ lailai.

### SENEGAL

Ọgbẹni Leopold Sengbor Alokoso Ijọba yio ba ọkọ ofurufu kuro ni ilu ni ọtun la lati wa ṣe ibẹwo ọjọ mẹjọ si orilẹ Naijiria.

### ENUGUN

Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati nwọn ri ọgbẹni Eugene ti o nṣiṣẹ iwe irohin ti o gbe mọto ti Ijọba ṣẹṣẹ ra fun u si ẹgbẹ ọna ti o si wọ inu igbo lọ pokunso, nwọn ti gbe oku rẹ lọ si Ile Iwosan lakulaku fun ayẹwo.

### ONITSHA

Adajọ Ile ẹjọ giga ti ṣe idajọ pe ki ọdaran kan, Emmanuel Ezeolisa lọ si ẹwọn ọdun mẹfa nitoripe o ji apọ agbado mẹjọ ti iye owo wọn jẹ £51 4s gbe.

### KONGO

Ọrọ di pẹẹntuka nigbati awọn Ọkunrin mẹwa kan gbe ibọn ọkọ ati ida ti nwọn ni awọn fẹ pa olori Ijọba wọn ọgbẹni Kasabu-bu ṣugbọn awọn Ọlọpa ti mu awọn enia na.

### ONITSHA

Owo kan (£1 000) ti awọn Ọlọṣa kan jigbe ninu ile ọgbẹni Egbuna, ni awọn Ọlọpa nu ti ri ninu koto kan ni ẹhinkule ile ọmọ ọdọ rẹ.

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 572 MONDAY, APRIL 6, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pẹlu Imọle Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni o ngbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun n... (1957) sehin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Ra... fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ...aiti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16, BAMGBOṢE STREET,
PHONE 21985, LAGOS.

# OBINRIN KAN JONA SINU AHERE

BENDE:— Gbogbo ilu Afara ni agbegbe Bende ni o gbojikan fun ipohunrere ẹkun nigbati irohin kan kakiri ilu wipe ina jo Iyaafin Ahudie Nwokenkpa pa bamubamu larin ọsẹ ti o kọja yi nigbati ijamba ina nla kan ṣẹlẹ.

Onirohin fi ye wa wipe Iyaafin na lọ si inu oko rẹ lati lọ tu awọn gbaguda diẹ ti yio ta ni ọja irọlẹ ni o ba da ina lati le sun iṣu jẹ, ki o to gba ọna ọja lọ.

Ṣugbọn bi o ti da ina na tan ti o si ko iṣu na le tan ni o ba mo ri gba inu ikoko lati ma ba iṣẹ rẹ lọ

Were ni atẹgun nla bẹrẹ si ifẹ ti o si kọju ina ti o da ti ina na fi ran mọ igbo suru kan ti o wa ni tosi oko na.

Lai fa ọrọ na gun ọrọ wipe gbogbo Igbo bẹre si jo kakiri bi Iyaafin na ti ri bẹ lo ba sare wọ inu ahere lati le ko awọn aṣọ rẹ jade ki o ma ba jọna.

Bi o ti wọ inu ahere lọ ini eefi ina na ba di mọ nu ile ti ko si riran mọ.

Ka wi ka fọ, ina yi tun bẹrẹ si ran mọ ahere ti o fi jẹ wipe Obinrin yi ko tilẹ ri ọna jade mọ, ko tilẹ le kigbe si ẹnikan rara titi ina na fi jo pa.

Irohin fi ye wa pe ni ọjọ keji ni nwọn to le lọ gbe oku Iyaafin na lọ si Ile Iwosan ti ilu uwaoia fun ayẹwo

Atun gbọ wipe Ọpọlọpọ ohun Oko ati ohun ini ni ina na bajẹ eyiti o le ni igba pọnun ( £ 200).

## Ọlọla Azikiwe Kiṣe Ẹni Abuku

Lati oju ewe kini.

"ọro rirun" kan ti ọkan ninu awọn Minista Ipinlẹ Ariwa sọ si Azikiwe jẹ eyiti o ya ẹnikẹni lẹnu, sugbọn o wa dupẹ lọwọ Alagba Aamadu Bello, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa fun aforijin ti o tete tọrọ lọdọ Ọlọla Azikiwe pe, ki o maṣe binu si ọrọ na.

Mallam Ibrahim Gusau wa ṣe alaye pe, Ọlọla Azikiwe ki iṣe ti ẹnikanṣoṣo, ti gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin ni ọlọla Azikiwe, ọrọ abuku si ọlọla na si jẹ ọrọ buku si gbogbo awọn enia orilẹ ede yi.

Lẹhin eyi ni Alhaji Abubakar Tafawa Balewa wa dide ti o si ṣe alaye pe, ọlọla Azikiwe ki iṣe ẹni abuku, ẹnikẹni ko si gbọdọ sọrọ ti ko dara si, bẹni ọwọ ati irẹlẹ ti o tọ ati eyiti o yẹ, ni gbogbo ara ilu gbọdọ ma a fun un bi iru enia bẹ, ko ba fẹ ki gbadogbadọ ki o gbađo lọwọ on.

ASUNNA—OWO

Lẹhin ọpọlọpọ ariyanjinyan ni gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na wa gba ti gbogbo wọn si fi ọwọ si i pe ọkẹ mẹta pọunun tabi ẹgba a mẹrinlelọgbọn pọnun (£63,160) ti Apapọ Ijọba fẹ fisilẹ dara lati na fun Afin Ọlọla Azikiwe fun ọdun yi.


AH! REMEMBER THAT

**The Social Dandies**

*PRESENTS*

**An Eid–Ul–Kabir Dance**

AT

**FORSTER CENTENARY HALL**

22, Ọdunlami Street, Lagos On Sunday 26th April 1964 (Sunday Ọdun Ileya) at 6 p. m. till dawn

*Music by one and only*

NEW TIME TAPE RECORDING
BASHY & HIS YOUNG STARS ORCHESTRA

Ladies and Gents, seize this opportunity and come and listen to the latest heats of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo M. B. E., Broadway Dandies of Ghana on the New Time Recording Enterprises and Bashy & His Young Stars Orchestra. Be there in time to avoid rushing.

**Tickets: 4/– Flat**

Tickets now on sale at 3, Olushi Street Lagos 16, Bamgboṣe Street, Irohin Imọlẹ's Office Wẹmimọ Alakija 41 Denton Street, Ebute-Mẹtta.



## AKARA TU S'EPO!

**Iwe Itumọ Ala na ti de**

Eyi ni lati kede fun awọn onkawe Irohin Imọlẹ pe Iwe Itumọ Ala lati ọwọ Joseph Alala ti jade fun tita nisisiyi. Iwe Ala yi yatọ si Iwe ala miran nitoripe Odu Ifa ni nwọn fi tumọ rẹ Egbogi jaburata si wa ninu rẹ pẹlu. Tete ra tirẹ ki o to tan.

Iye Owo:— Igo kan 5/
Dọsini 36/-

J. O. SHOYINKA
N2/99 Shittu Street
Ibadan



Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgboṣe Street, Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M.S. Grammar School) P. O. Box Bariga (6/4/64)